# ASÁN TI O WÀ NINU ILEPA AYÉ

**Oniwasu 1:1-18; 2:1-26**

**ẸKỌ 376 --- FUN AGBA**

**AKỌSORI: "Ọlọrun fun enia ti o tọ li oju rẹ̀ li ọgbọ́n, ati ìmọ ati ayọ̀: ṣugbọn ẹlẹṣẹ li o fi ìṣẹ́ fun, lati ma kó jọ ati lati ma tò jọ ki on ki o le ma fi fun ẹni rere niwaju Ọlọrun" (Oniwasu 2:26).**

**I Asán ti o Wà Ninu awọn ohun Ayé Yii**

1 Oniwaasu fi hàn pe kò si ohun titun ninu ayé. Ohun gbogbo n lọ ni ayika ni, Oniwasu 1:1-11; Orin Dafidi 62:9; Romu 8:20

2 O fi àya rẹ̀ si wiwadii ọgbọ́n ni ti ohun gbogbo ti a n ṣe; o ri i pe imulẹmofo ni, Oniwasu 1:12-18; 7:23-25; 1 Tẹsalonika 5:21

3 O dán iré-ayọ ati ọti-waini, ile pupọ ati ọgba-ajara, fadaka ati wura, awọn alo-ohun-elo-orin ati awọn akọrin wò, ṣugbọn gbogbo rẹ̀ jẹ́ asán nipa ohun pataki ti o dara, Oniwasu 2:1-11; Luku 12:19

4 Nigba naa ni o wo ọgbọ́n ati were, o si ri i pe ọgbọ́n ta were yọ gẹgẹ bi imọlẹ ti ta okunkun yọ, ṣugbọn eṣe kan ṣoṣo ni o n ṣe gbogbo wọn, Oniwasu 2:12-17; 8:1; Orin Dafidi 49:10; Owe 17:24

5 O woye nipa iriri pe igbadun tootọ tabi ohun rere kò ti ipa ilepa eniyan wá, bi kò ṣe lati ọwọ́ Ọlọrun, Oniwasu 2:18-26; Jobu 27:16, 17; Owe 28:8

## ALAYE

### Ilepa Sọlomọni fun ohun Ayé Yii

Eredi Iwe Oniwaasu ni lati fi hàn bi ilepa ẹdá fun ohun ayé yii ti jẹ́ ohun asán tó ati bi o ti yatọ si ilepa ti ẹmi ti o kún fún ibukun ti n ti ọdọ Ọlọrun wá ninu ọgbọ́n tabi isin tootọ. O fi hàn bi awọn ohun àlumọni ohun ayé yii ti kùnà tó lati tẹ́ ọkàn lọrun ati bi ọgbọ́n Ọrun ṣe jẹ́ olubori ohun rere gbogbo.

A sọ fun ni pe nigba ti Sọlomọni wà ni ọdọ ni o kọ orin rẹ̀ ti a n pe ni "Orin Sọlomọni," nigba ti ifẹ Ọlọrun n jo geregere ninu ọkàn ati igbesi-ayé rẹ̀, Nipa ifọrọwerọ ati owe ni o ti n sọ ohun ti ẹmi jade. O dabi ẹni pe igba ti Sọlomọni di agbalagba ni o kọ Iwe Owe, Iwe Oniwaasu si jẹ́ aṣaro igba ogbó rẹ̀.

Awọn Ju a maa ka Iwe Oniwaasu lọdọọdun nigba Ajọ-Agọ -- Iwe ọfọ ti o ga ju lọ ni akoko àse ti o kún fún ọ̀pọlọpọ ayọ̀.

Nigba ti Sọlomọni wà ni ọmọde ti a si fi jẹ ọba lori Israẹli, ọkàn rẹ̀ fa si Ọlọrun. O n fẹ́ alaafia, ododo ati ọgbọ́n lati mọ bi a ti ṣe idajọ awọn eniyan ti o pọ̀ bayii. Ọlọrun fun un ni ifẹ ọkàn rẹ̀, o si fi ọrọ̀, okiki ati ọlá kun un. Ijọba rẹ̀ lo ni ogo ju gbogbo ẹnikẹni lọ ninu ọba ayé. Awọn eniyan n wá lati opin ayé lati gbọ́ ọgbọ́n Sọlomọni.

O dán ohun gbogbo wò ni ayé lati mọ eyi ti o le mú ayọ̀ bá ọkàn eniyan. O ṣe akiyesi pe ohun gbogbo ni o n yi ni ayipo. Iran kan lọ, iran miiran si dé. Oorun là, oorun si wọ̀, o si yara lọ si ipo rẹ̀ nibi ti o ti là. Afẹfẹ n fẹ́ yika nigba gbogbo, o n lọ lati iha guusu si iha ariwa o si n lọ bẹẹ ni iyika rẹ̀. Gbogbo odo ni n ṣan sinu òkun, lẹyin naa wọn a tun ṣàn pada si ibi ti wọn ti ṣàn wá. Kò si ohun titun labẹ oorun. Ohun ti o wà nisisiyii ti wà tẹlẹ ri.

O fi ọkàn rẹ̀ si ati wá ọgbọ́n ati iwere. O ri gbogbo iṣẹ ti a n ṣe labẹ oorun, o si ṣe akiyesi pe eyi ti o wọ́ ni a kò le mu tọ́, ati eyi ti o ni abuku ni a kò le ka.

### Ijatilẹ Ninu Iré-Ayọ̀

Siwaju si i, Sọlomọni tun dán afẹ́ ati ọti-waini wo lati ri ki ni ayọ̀ ti oun le ri ninu iré-ayọ̀. O sọ nipa ẹrin pe, "Iwere ni," ati nipa iré-ayọ̀ pe kò si ohun danindanin ninu rẹ̀. O dán ile ọti wò ṣugbọn o ri i pe ẹlẹya ni ọti-waini, alariwo ni ọti lile; o sọ bayii pe, "Iwọ máṣe wò ọti-waini pe o pọn … ninu ago."

Paulu wi pe, “Ẹrú ẹniti ẹnyin ba gbọ tirẹ̀ li ẹnyin iṣe” (Romu 6:16). Iye eniyan meloomeloo ni o ti di ẹru ọti lile! Sọlomọni ri i pe gbogbo rẹ̀ asán ni.

**Kò Si Itura ninu Ile Kikọ Ati Ọgba Itura**

Sọlomọni tun kọ́ ile daradara, o si gbin oniruuru igi eleso, o ṣe ọgbà ajara ati adagun pupọ ati gbogbo nnkan wọnni ti o dara fun oju lati wò. O fi ọdún mẹtala kọ́ ile ara rẹ̀. Gbogbo ohun ti owó le rà ati iṣẹ ẹwa ọlọna ni a fi kún gbogbo ile naa. O ṣe ọgba itura daradara, o si gbịn oniruuru igi eleso sinu wọn, o si ṣe adagun omi lati maa bomirin wọn. Diẹ ninu awọn adagun omi naa wa titi di ọjọ oni. O ya ọ̀pọlọpọ ilẹ sọtọ lẹba ile rẹ̀ lati maa fi ṣe afẹ́, o si fi ododo ati eweko daradara yi wọn ká. O ni ifẹ si ohun gbogbo ti o lẹwa. Ki a kuku sọ pe o ṣe paradise fun ara rẹ̀ ni ayé yii niwọn bi ẹda ti le ṣe mọ̀. Ṣugbọn ile daradara, ọgba itura daradara, ohun gbogbo ti owo ati ọgbọ́n ẹda le ṣe jẹ́ asán ati imulẹmofo ati ibanujẹ ọkàn.

**Orin ati Iwe**

O dán orin ati oye iwe wò, eyi ti o jogun, lai si aniani, lati ọdọ baba rẹ̀ Dafidi. A sọ fun wa pe o kọ ẹgbẹrun orin o le marun-un o si pa ẹgbẹẹdogun òwe. O kọ nipa igi, lati igi kedari Lebanoni daradara titi de igi hissopu keekeekee ti o n hù lara ogiri. O kọ nipa awọn ẹranko igbẹ, awọn ẹyẹ oju ọrun ati ẹja inu okun. Okiki rẹ̀ tàn ká gbogbo orilẹ-ède. Awọn ọba ayé wá lati gbọ́ ọgbọ́n rẹ̀.

**Ẹṣin Daradara ati Kẹkẹ Ẹlẹṣin**

O ni awọn ẹṣin ati kẹkẹ ẹlẹṣin ti o dara ju lọ: ọkẹ meji eekan fun ẹṣin rẹ̀ ati ẹgbaafa ẹlẹṣin. O ni maluu lọpọlọpọ ju gbogbo ẹni ti o wà ni Jerusalẹmu lọ. Oun ni o kọ́ mu ọkọ ogun ti ijọba Israẹli ni lọ si ori okun. Gbogbo awọn orilẹ-ède ti o yi Jerusalẹmu ká ni o n bá ṣowo.

O fi ọgbọ́n wé iwere, o si ri i pe ọgbọ́n ta were yọ gẹgẹ bi imọlẹ ti ta okunkun yọ; sibẹ èṣe kan naa, ani ikú, ni o n ṣẹ si gbogbo wọn.

**Iroyin Tootọ**

“Sọlomọni ọba si pọ̀ jù gbogbo awọn ọba aiye lọ, li ọrọ̀ ati li ọgbọ́n. Gbogbo aiye si nwá oju Sọlomọni lati gbọ́ ọgbọ́n rẹ̀, ti Ọlọrun ti fi si i li ọkàn” (1 Awọn Ọba 10:23, 24).

Nigba ti Ayaba Ṣeba tọ Sọlomọni wá lati fi àlọ̀ dán an wò, ti o si ri ọgbọ́n rẹ̀, ile ti o kọ́, ounjẹ tabili rẹ̀ ati iduro awọn iranṣẹ rẹ̀, kò ku agbára kan fun un mọ́. O wi pe, “Otitọ li ọ̀rọ ti mo gbọ́ ni ilẹ mi niti iṣe rẹ ati niti ọgbọ́n rẹ.”

**Itẹlọrun lati Ọwọ Ọlọrun**

Sọlomọni dán ohun gbogbo wò ni ayé dé ogogoro – okiki, ọlá, iyi, ọrọ̀, ile daradara, kẹkẹ ẹlẹṣin ati ẹṣin, ifẹ obinrin, orin ati orin kikọ, iwe kikọ, kikọ ọrọ orin. Kò si ohun ti kò danwo lati wá ohun ti yoo tẹ́ ọkàn rẹ̀ lọrun. Ohunkohun ti oju rẹ̀ ba fẹ́, oun ki i fi du u. O ṣe awari ohun gbogbo ki oun ki o ba le ri eyi ti o dara ati ohun ti o le fi idunnu pupọ fun awọn ọmọ-eniyan ni ayé. Ṣugbọn Ọlọrun ti fi aafo kan sinu ọkàn ẹdá ti o jẹ pe Ọlọrun tikalara Rẹ̀ nikan ni o le di i. Bi ko ṣe pe Ọlọrun ba fi ara Rẹ̀ ati ifẹ Rẹ̀ di aafo naa, kò si ohunkohun laye ti o le di i. Iriri ni o kọ́ Sọlomọni pe itẹlọrun ati ayọ̀ pipe, ọwọ Ọlọrun nikan ni o ti n wá.

**Apọsteli Paulu**

Ẹ jẹ ki a fi ilepa Sọlomọni wé ti Paulu, Apọsteli awọn Keferi. Oun pẹlu nọga lati dé gongo okiki. A kọ ọ ni ẹkọ ni ẹsẹ Gamaliẹli, ọkan ninu awọn olukọ ti o ga ju lọ ni igba ayé rẹ̀. O ti bẹrẹ si gun oke aasiki dé ori ṣugbọn Jesu ti Nasarẹti di igbesẹ rẹ̀ mú ni ọjọ kan. Gbogbo ilepa rẹ̀ yi pada. O jiya ohun pupọ ṣugbọn o ri ohun gbogbo ti o ṣe alaini ninu Jesu: ọgbọ́n, ododo, isọdimimọ́, ati irapada. Kò si ohun ti o le yà á kuro ninu ifẹ Ọlọrun. Ni opin ayé rẹ̀ o kọwe bayii pé, “Emi ti jà ija rere, emi ti pari ire-ije mi, emi ti pa igbagbọ́ mọ́: lati isisiyi lọ a fi ade ododo lelẹ fun mi” (2 Timoteu 4:7, 8). Igbẹyin rẹ̀ kún fún iṣẹgun. Ketekete ni orukọ rẹ̀ hàn ninu Ijọ Ọlọrun ninu awọn òpó igbagbọ́, ṣugbọn pẹlu gbogbo ọgbọ́n ati ọrọ̀ Sọlomọni kò le ṣe aṣeyọri.

**Alaafia Nipasẹ Jesu**

O di mimọ̀ fun Sọlomọni ni opin ayé rẹ̀ pe ọwọ Ọlọrun nikan ni alaafia ati iṣẹgun ti n wá, pe gbigba ọ̀na ayé lati lepa alaafia jẹ́ ohun asán ati imulẹmofo.

Bi Sọlomọni pẹlu gbogbo anfaani ti o ni lati jẹ afẹ́, bá kunà lati ri alaafia, lai si Ọlọrun, ta ni oluwa rẹ̀ ti o tun le ri i? Alaafia ninu ayé yii jẹ́ ipin awọn ẹni iwa-bi-Ọlọrun nikan. Peteru wi pe, "Ẹniti ẹnyin fẹ lairi, ẹniti ẹnyin gbagbọ, bi o tilẹ ṣepe ẹ kò ri i nisisiyi, ẹnyin si nyọ ayọ̀ ti a kò le fi ẹnu sọ, ti o si kun fun ogo" (1 Peteru 1:8).

Nipari awari rẹ̀ Sọlomọni wi pe, "Opin gbogbo ọ̀rọ na ti a gbọ́ ni pe: Bẹ̀ru Ọlọrun ki o si pa ofin rẹ̀ mọ́: nitori eyi ni fun gbogbo enia" (Oniwasu 12:13).

Jesu wi pe "Nitoripe ère kini fun enia, bi o jèrè gbogbo aiye, ti o si sọ ẹmi rẹ nù? tabi kili enia iba fi ṣe paṣiparọ ẹmi rẹ̀?" (Matteu 16:26).

Paulu wi pe, "Ṣugbọn iwa-bi-Ọlọrun pẹlu itẹlọrun ère nla ni" (1 Timoteu 6:6).

**AWỌN IBEERE**

1 Iwe meloo ni Sọlomọni kọ ninu Bibeli?

2 Nigba ti a fi Sọlomọni jọba, ki ni o bèere lọwọ Oluwa?

3 Ki ni Sọlomọni sọ nipa òòrùn, afẹfẹ ati awọn odò?

4 Ki ni Sọlomọni n gbiyanju lati ri ninu ayé?

5 Nibo ni Sọlomọni ti ri ohun ti i ṣe orisun alaafia tootọ?

6 Fi igbesi-ayé rẹ̀ wé ti Paulu.

7 Ki ni Jesu sọ nipa jijèrè gbogbo ayé yii?